**Lakaye Ọrọ**

'ATI pẹlu nigbati ẹnyin ba ngbawẹ, ẹ maṣe dabi awọn agabagebe ti nfajuro, nwọn a ba oju jẹ, nitori kinwọn ki o ba le farahan fun enia pe nwọn ngbawẹ. Lootọ ni mo wi fun nyin, nwọn ti gba ere wọn na.


# Irohin Yoruba

NO. 821 MARCH 1 — MARCH 7, 1961 KOBO MEJI (2D)





O dara pupọ fun Ikọ ti o nyọ awọn ẹbi rẹ lẹnu
O wa fun tita kakiri ile-egbogi


# AWỌN OBIRIN YIO NI IPO NINU IJỌBA IBILẸ IPINLẸ IWỌ-ORUN

IBADAN

**NIGBATI Oloye S. L. Akintọla, Alakoso Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun nsọrọ ninu ipade ase apejẹ ti awọn Ẹgbẹ Alaṣẹ Ijọba Ibilẹ Ipinlẹ Iwọ-Orun [ Western Nigeria Union of Local Authorities ] pe si Gbọngan Apejọ Ipinlẹ Iwọ-Orun ni Ibadan, ni ọjọ Ẹti ti iṣe ọjọ kẹtadinlogun oṣu ti o kọja yi, o ni awọn obirin Ipinlẹ Iwọ-Orun Najiria ni ipinṣẹ tiwọn pataki ti nwọn yio ṣe ninu eto iṣẹ Ijọba Ibilẹ ipinlẹ na.**

O tun sọ pe Ijọba yio si wa onakọna lati ṣe eto bi nwọn yio ti ṣe ma a ni aṣoju tiwọn ninu gbogbo eto iṣẹ Ijọba Ibilẹ ni ọjọ iwaju.

Oloye Akintọla si ṣe alaye siwaju pe, on ṣe akiyesi pe, lẹhin ti a ti gba Ominira Ijọba tan, eto iṣẹ amojuto-ilu awọn Igbimọ Ijọba Ibilẹ tubọ npeleke si i, ṣugbọn awọn Igbimọ na mba iṣẹ wọn lọ deede lati fihan pe, Naijiria ti peye to lati gba Ominira Ijọba na.

**ILERA, ALAFIA**

O tun sọ wipe, bi awọn Igbimọ Ijọba Ibilẹ, ti gbogbo awọn ara ilu gbojule pataki, ba ti ni akikanju to, ti nwọn si jafafa ninu iṣẹ wọn to, ni ilera ati alafia yio fi wa 'nu igbesi-aiye gbogbo ara ilu to.

Oloye Akintọla ni iṣẹ awọn Igbimọ Ijọba Ibilẹ ni lati ṣe [illegible] Amojuto-atunṣe-ilu, ki nwọn ma a gbe ẹkọ awọn ara ilu ga siwaju, lati pa ofin ati eto Ijọba mọ ati lati daabobo aṣa-ibilẹ ati nkan iṣẹdalẹ wọn.

Oloye Akintọla si t[illegible] ọrọ pataki kan fun wọn bayi pe, gẹgẹbi aye enia pataki larin ilu, Aṣoju Igbimọ Ijọba Ibilẹ ga ju awọn ara ilu yoku lọ, bi o ba si ni ẹrannu tabi ẹmi-igbẹsan, yio di wahala si gbogbo ara ilu lorun. Nitorina, gbogbo awọn Alaṣẹ Ijọba Ibilẹ Ilu gbọdọ sọ

Wo oju ewe kẹrindinlogun



Ọlọla Adesọji Aderẹmi, Gomina Ipinlẹ Iwọ-Orun

# Oluwa ṣ'alaye

NINU Iwe "Irohin Yoruba" ti ọsẹ ti o kọja, loju ewe kinni, a ṣe irohin nipa rogbodiyan ti o wa larin awọn ẹbi Oloye Oluwa Eko, a si sọ alaye ti awọn ti oye na tọ si ṣe nipa akata-kiti ọrọ oye na.

Alaye ti Ọgbẹni Abudu Karimu Balogun, ẹniti on pẹlu Ọgbẹni Abudu Rashidi 'Afuwapẹ' ndu oye na ṣe ninu Iwe "Irohin Yoruba" ọsẹ ti o kọja nipe on gan an ni oye na tọsi, ati pe nigbati Ọba Adeniji Adele Keji, Ọba Eko wa si Minna, ti on si gba a ni alejo, ti awọn da ọrọ oye na silẹ, o ni Ọba Adele fi on lọkan balẹ pe bi awọn ẹbi Oluwa ba ti panupọ yan on, ko ni si isoro fun on lati gba a gẹgẹbi Oloye.

Wo oju ewe kẹrindinlogun



KARIMU BALOGUN

# Musulumi ati Onigbagbọ bẹrẹ awẹ ni ọjọ kanna

**NI ọjọ Ẹti ti iṣe ọjọ kẹtadinlogun oṣu ti o kọja yi, awọn Musulumi ati Onigbagbọ ni Naijiria bẹrẹ awẹ gbigba lọjọ kanna. Eyi jẹ akoko ti iru nkan bẹẹ yio ṣẹlẹ larin awọn ẹlẹsin mejeji, o si tun jẹ ohun iyalẹnu nla fun ọpọlọpọ enia. Ṣugbọn loju awọn ọjọgbọn, o jẹ isami ohun rere fun awọn ẹlẹsin mejeji yi ni ilu Naijiria.**

Ninu Iwe "Irohin Yoruba" ti ọsẹ yi, ẹnyin onkawe wa yio ka nipa ọrọ Awẹ ti awọn Musulumi ati ti Lẹnti ti awọn Onigbagbọ loju awọn ewe miran.

Apapọ oṣu mimọ yi fun awọn ẹlẹsin memeji yi, gẹgẹbi awọn ọjọgbọn ti wi, yio jẹ isami rere fun ilu wa. Oluwa ko jẹ ki o jẹ bẹ ẹ. Ṣugbọn eyi ko gbọdọ ya ẹnikẹni lẹnu.

Ninu Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun, Musulumi ati Onigbagbọ ni nwọn jọ nṣe eto ti o si ngun rege-rege. Ninu Ijọba Ipinlẹ Ariwa paapa lo tilẹ jẹ pe awọn Musulumi lo pọju, awọn pẹlu Onigbagbọ ni nwọn jọ nṣe akoso Ijọba papọ.

Ninu Apapọ Ijọba Naijiria ẹwẹ, o fẹrẹ ma si iyatọ ninu awọn alaṣẹ Ijọba na fun eto ati alafia ilu. Fun awọn ti nwọn nyan ara wọn si ọtọ nipa pe ẹsin ko ri bakanna, eyi yio jẹ apẹrẹ pe ẹsin-kẹsin ti enia ba nsin, inu mimọ, iwa rere, ni pataki-julọ. E ku orugbẹ l'ọtun l'osi! Oluwa jẹ ki ẹmi o gba a jalẹ.

# Akede Ọna Igbala

## Awẹ ha ngbani la bi?

LATI ibẹrẹ oṣu yi ni gbogbo awọn ọja ti nkun fun awọn enia ti nwọn nlọ lati ra awọn nkan ti nwọn yio fi gba awẹ. Orişirişi imurasilẹ miran si tun ni gbogbo awọn Imale tun nṣe fun eyi lati ma fi gba awẹ wọn na,

O fẹrẹ jẹ pe ọmọde ati agba ni o ma nsare fun imura awẹ. Eeṣe ti a fi nṣe eyi?

Lẹhin ọpọ iwadi ni awọn enia ti o jẹ akikanju ninu isin Imale wa fi nhan pe ohun pataki ti o ngmu ki awọn ma gba awẹ ni lati tọrọ idariji fun ẹṣẹ ti awọn ti ṣẹ. Awọn miran ẹwẹ sọ pe awọn ngb'awẹ ki awọn le ni ibẹru Ọlọrun ninu okan awọn nitoripe ninu ibẹru Ọlọrun ni enia ti le ni ogbọn ati itẹsiwaju.

### ITỌRẸ AANU

Ẹlomiran ẹwẹ fẹnu kan fun wa pe awọn ko gbọdọ hu iwa buburu kan 'nu awẹ na titi yio fi pari, awọn si nilati ma ṣe itọrẹ aanu fun awọn talaka ati opo ati awọn alejo gbogbo, 'toripe laiṣe bẹ ẹ, asan ni awẹ ti awọn ngba ja si ni ọdọ Ọlọrun. Bẹni awọn ko le wu Ọlọrun nitoripe iṣẹ rere ni Ọlọrun mbere lọdọ awọn ti awọn fi ngbawẹ.

Awẹ ha ngmu wa wu Ọlọrun bi? Awẹ gbigba ki iṣe ohun ti o buru niwaju Ọlọrun ti a ba gba a ni ọna ti o dara ninu eyi ti Ọlọrun paapa tọka wa si pe ki a ṣe. Ẹ gbọ ohun ti ọrọ Ọlọrun sọ fun wa nipa rẹ:

"Ati pẹlu nigbati ẹnyin ba ngbawẹ, ẹ maṣe dabi awọn agabagebe ti nfajuro; nwọn a ba oju jẹ, nitori ki nwọn ki o ba le farahan fun enia pe nwọn ngbawẹ. Lotọ ni mo wi fun nyin nwọn ti gba ere wọn" (Matteu 6: 16).

### AKIYESI

Ṣugbọn a nilati kiyesi pe eyi ko mu igbala wa fun emi wa tabi sọ wa di ẹni mimọ niwaju Ọlọrun Alaye. Ẹ jẹki a kiyesi ohun ti Ọrọ Ọlọrun tun sọ fun wa nipa iṣẹ wa ninu igbala: "Nitori ore-ọfẹ li ati fi gba nyin la nipa igbagbọ; ati eyini ki iṣe ti ẹnyin tikara nyin ẹbun Ọlọrun ni: Ki iṣe nipa iṣẹ, ki ẹnikẹni ma ba ṣogo'" (Efesu 2: 8, 9).

Ọlọrun ko le ti ipa iṣẹ wa gba wa la bẹni ododo wa ko to ohun kan niwaju Rẹ. "Gbogbo wa si dabi ohun aimọ, gbogbo ododo wa si dabi akisa ẹlẹgbin" (Isaiah 64: 6).

Ọna kanṣoṣo ti a le fi wu Ọlọrun nipa igbala tabi lati jẹ olusin pipe niwaju Rẹ ni lati gba Jesu Kristi Ọmọ Rẹ gbọ. Jesu Kristi ni O ku ni ori igi agbelebu fun imukuro ẹṣẹ wa, ẹjẹ Rẹ nikan na si ni o le wẹ wa nu ninu aiṣedede wa gbogbo ti o si tun le mu wa wu Ọlọrun pẹlu. O ku o si jidide bẹni O ti fi ara Rẹ fun iya ati iku wa ki awa le ni iye ni orukọ Rẹ.

### IRANLỌWỌ

Nitotọ awẹ nṣe iranlọwọ fun wa lati ni irẹpọ pẹlu Ọlọrun wa, nitoripe bi inu wa ba kun fun ọpọ onjẹ nigbamiran awa le ṣe aibikita. Ṣugbọn kini itumọ ohun ti a ti itori rẹ gba awẹ ti a ko si tẹ le e? Nitori Jesu Kristi sọ pe On ni ọna ti a le gba de ọdọ Ọlọrun ati pe ẹniti o ba ti ri On ri Baba on, ẹniti iṣe Ọlọrun.

Ṣugbọn kini o ṣe ti a ko le gba Jesu Kristi na gbọ bi a ba fẹ ri oju rere Ọlọrun. Ko si ọna miran ti a le gba lati wu Ọlọrun tabi ri oju rere Rẹ lai gba Ọmọ Rẹ kanṣoṣo na gbọ ti O ran wa salyeọ lati gba gbogbo araiye la, Jesu Kristi. A ko le ni irẹpọ kan pẹlu Rẹ bi o ti wu ki o ri lai jẹwọ ẹṣẹ wa fun Kristi na.

Eeṣe ti a ṣe nfi ẹtẹ silẹ ti a fi npa lapalapa? A fi ọna silẹ a nrin ninu igbẹ. Nigbagbogbo ni a ma nwa idariji fun awọn ohun ti a ti ṣe, ṣugbọn ki iṣe ọna ti a ngba yi ni a le ri idariji fun ẹṣẹ wa.

Awọn miran ngbawẹ, nwọn si ngbadura, ṣugbọn itumọ ohun ti nwọn nṣe ko ye wọn. Ẹ ha ṣe ti a fi nṣe ohun ti ko ye wa ti a ko si bere? Owe Yoruba ni o sọ pe "A bere ki i ṣina."

### AWẸ TULASI

Awọn onigbagbọ ma nkun fun awẹ ati adura lati ri pe nwọn ni idapọ mimọ pẹlu Ọlọrun, ṣugbọn nwọn ti ni igbagbọ ninu Jesu Kristi lati inu ọkan wọn siwaju eyi nitori nwọn mọ wipe lai si igbagbọ ninu Jesu Kristi Ọmọ Ọlọrun asan ni awẹ ti awọn ngba.

Bibeli ti iṣe Ọrọ Ọlọrun sọ nipa awẹ ṣugbọn a ko kan an nipa fun ẹnikẹni lati gba a. Ọpọlọpọ awọn enia ni nwọn nfi tulasi gba awẹ na, ẹlomiran ẹwẹ si ma a nfi awẹ na di ara rẹ lọwọ lati rin ni ọna Ọlọrun, ti awọn miran nti ipa eyi fi ebi pa ara wọn. Ṣugbọn lai si ijẹwọ ẹṣẹ niwaju Jesu asan ati imulẹmofo ni ohun ti a nṣe lẹ.

Ṣugbọn Ọlọrun nreti gbogbo wa lati wa fun idariji nipasẹ Jesu Kristi, ki iṣe nipasẹ awẹ tabi iṣẹ rere ti a nṣe. "Pe, li orukọ Jesu ni ki gbogbo ekun ki o ma kunlẹ, awọn ẹniti mbẹ li ọrun, ati awọn ẹniti mbẹ ni ilẹ, ati awọn ẹniti mbẹ nisalẹ ilẹ; ati pe ki gbogbo ahọn ki o ma jẹwọ pe, Jesu Kristi ni Oluwa, fun ogo Ọlọrun Baba" (Filippi 2: 10, 11).

Iwọ ọrẹ wa ti o nka iwe yi, njẹ Akede Ọna Igbala nfi ọna han ọ loni pe iwọ ko le gba ara rẹ la, bẹni iṣẹ ọwọ rẹ ati awọn iwa rere ti o nhu ko le sin ọ de iwaju Ọlọrun a fi igbagbọ ninu Jesu Kristi nikan ni o le fun ọ ni igbala! Nitori Jesu paapa sọ fun wa pe, "Ẹniti o ba gba Ọmọ gbọ o ni iye ainipekun, ẹniti ko si gba Ọmọ gbọ ki yio ri iye ṣugbọn ibinu Ọlọrun mbẹ lori rẹ" (Johannu 3: 36).

Njẹ iwọ ha le duro de ibinu Ọlọrun bi? Tabi agbara rẹ ha le da ibinu Ọlọrun duro lori rẹ bi, laiṣe pe iwọ gba Jesu Kristi ni Olugbala rẹ? Njẹ fi eyi kẹwọ ki o si mọ Jesu ni Oluwa ati Olugbala rẹ loni.


Nikehin wayi

abẹ infarungbọn to mu julọ




Ọbẹ Alafẹfẹ NACET Ọlọni

Trade enquiries to: R. E. HARDING & CO. LTD • LAGOS • ABA • KANO

# Ẹgbẹ Ansar-Ud-Deen Jos fi ipilẹ ile ẹkọ lelẹ



NI ojo Aiku ti i se ojo ... awọn Ẹgbẹ Young ... Ansar-Ud-Deen, ... Jos. ...

[illegible]

## FEDERATION OF NIGERIA SECOND DEVELOPMENT LOAN

[illegible]

Central Bank of Nigeria,
Lagos,
February, 1962.

# Awọn Ọlọpa Naijiria ni Kongo



[illegible]

## Adajọ ni ki ọdaran olowo ori lọ sanwo tabi ko lọ sẹ ẹwọn

[illegible]

## Ofo ẹmi

[illegible]

## Awọn ọmọ Ilobu ni Ghana ṣe ipade alarinrin

[illegible]

## Omọ odun meje ku sinu odo

[illegible]

## Balẹ Oluwatẹdo yan awọn Oloye

[illegible]

# CLASSIFIED ADVERTISEMENTS

Bi a ti ṣọwọ kọ awọn irohin ti o wa ni isalẹ yi ni a n ma a kọ awọn irohin ti a ba ri gba ti awọn eni ti o ba fi ṣọwọ si wa ba fi owo itẹjade ṣọwọ pẹlu gẹgẹbi akiyesi ti a tẹ jade ninu iwe "Irohin Yoruba" ọsẹ ti o kọja. Nitorina a bẹ gbogbo ẹnyin onkawe wa lati tẹle apẹrẹ na gẹgẹbi akiyesi ti a ṣe na.

[illegible]




# Eto ati eewọ ti o wa ninu awẹ Lẹnti

**( Lati ọwọ J. Olurebi Williams, Mushin )**

ITUMỌ "Lenti" jẹ akoko gbigba Aawẹ ati ikanu-ẹṣẹ fun iranti ijiya Jesu Kristi titi ti nwọn fi kan an mọ agbelebu, titi ti o fi ku ti nwọn si sin in sinu Isa Oku, ki o to wa ji dide ni idaji owurọ ọjọ kẹta.

Nitori idi eyi, gbogbo awọn Onigbagbọ-ododo (Christians) yika gbogbo agbaiye bẹrẹ awẹ mẹtalelogoji fun "Lenti" na ni ọjọ Ẹti (Friday) ti iṣe ọjọ kẹtadinlogun oṣu keji ọdun yi (17-2-61), nwọn yio si pari rẹ ni agogo mejila ọsan ọjọ Ẹti (Friday) ti iṣe ọjọ kọkanlelogbọn oṣu kẹta ọdun yi (31-3-61).

**ETO ẸSIN AGUDA**

Gẹgẹbi Eto Ẹsin awọn Aguda (Catholic) lati ọjọ kẹdogun oṣu keji ọdun yi (15-2-61) ti iṣe "Ọjọ Eeru" (Ash Wednesday) ni awọn Iranṣẹ Oluwa, Ijọ na ti sami eeru fun gbogbo awọn Ijọ na, ọrọ ti Iranṣẹ Oluwa si ka si etigbọ awọn Ijọ lẹhin ti o ti sami eeru yi fun wọn tan ka bayi pe:—

"Ẹ fi aṣọ ọfọ parọ aṣọ nyin, ki ẹ si fi ara nyin yilẹ eeru, ẹ jẹki a gbaawẹ, ki a si damije niwaju Ọlọrun, nitoripe Ọlọrun wa kun fun aanu, yio si dari ẹṣẹ wa jin wa."

Iṣẹ pupọ wa fun awọn onigbagbọ lati ṣe larin akoko iranti pataki yi, ṣugbọn awọn ohun ti o ṣe pataki julọ ni, lati ṣe eto isin ninu Ile Ọlọrun ati lati pa awọn eewọ ti o wa fun aawẹ "Lenti" gbigba na mọ.

**AWỌN EEWỌ AWẸ**

Orişirişi ẹya awọn Onigbagbọ ni o wa kakiri agbaiye nisisiyi, ṣugbọn eyikeyi ninu wọn ti o ba yapa kuro ninu ipamọ ilana awọn eewọ ti o wa fun awẹ yi, ko mu ifẹ Ọlọrun ṣẹ lati jẹki aawẹ na mọ ṣakaṣaka, ki o si jẹ itẹwọgba lọdọ Ọlọrun.

Eto Aawẹ Lenti ni pe, bi awọn Onigbagbọ (Christians) ba ti jẹ onjẹ alẹ tan lati fi gba aawẹ yi, o tun



J. OLUREBI WILLIAMS

* * *

di alẹ ọjọ keji ki nwọn to tun jẹun lati fi ṣinu aawẹ na.

Ninu gbogbo awọn ọjọ (Fridays) ti o wa larin aawẹ mẹtalelogoji yi, awọn Onigbagbọ ko gbọdọ jẹ ẹran tabi ohun ẹlẹjẹ rara, titi ti ọjọ Ajinde yio fi de ni ọjọ Aiku (Sunday) ti iṣe ọjọ keji oṣu kẹrin ọdun yi (2-4-61).

**ONIGBAGBỌ ODODO**

Awọn eewọ ti o wa ninu eto Lenti yi ni wipe, awọn Onigbagbọ-Ododo ko gbọdọ lu ilu fun ajọyọ tabi jo ijo ariya kankan rara larin asiko Lẹnti yi, nitoripe nwọn nfi awẹ na ṣe ikaanu fun ijiya ati iku Jesu Kristi, Olugbala gbogbo araiye ni.

Ẹṣẹ ni fun gbogbo awọn Onigbagbọ lati bu ẹnikẹni ni eebu tabi pẹgan ẹnikẹni ni arin akoko na nwọn ko tilẹ si gbọdọ binu si ẹnikẹni tabi ṣe ohun-ẹgbin rara pẹlu nwọn gbọdọ kun fun adura ati ironupiwada -ẹṣẹ nigbagbogbo, titi ti ọjọ Ajinde na yio fi de.

Aṣeyi-ṣamọdun.

***Ẹ ma a polowo ọja nyin sinu iwe "Irohin Yoruba"***


## tete gun RUDGE debẹ lasiko



Bẹni, iwọ yio ma a tete de nigbagbogbo bi o ba ni basikulu Rudge kan. Ko si irin mọ,ko si iduro fun awọn mọto ti nwọn to di ọna mọ. Ki o si ṣe iranti pe—o ko ni sanwo epo-mọto bi o ba ngun Rudge, nitoripe basikulu Rudge to gbojule nipa irinṣẹ rẹ ti nwọn ṣe daradara fun lilo titi aiye.
Yan ẹya iru eyiti o fẹ larin oniruru awọn ti nwọn kun ni ọda ti o ndan yinrinyinrin, ki o si ma a gbadun ogo ati ominira ti o ni lori wipe, o ni basikulu ti o yara julọ loju ọna.

JOHN HOLT

NI O NTA A KAKIRI YIKA GBOGBO NAIJIRIA.

